Ogun Ita'ja

E Polowo oja yin sinu Iwe Irohin Eliti-Ofe, Kia L'oja o ta.

ELETI OFE

A-NJU-WON KO SE WI L'EJO

U. T. C.

DEPARTMENT STORE

SERVES

YOU

WELL

VOL. XI No. 614. LAGOS, SATURDAY, MARCH 7 — MARCH 13, 1959. KỌBỌ MEJI (2d)

# Enmo! Egungun Di Enia Ni Ijebu-Ode

**IJẸBU-ODE.** A gbọ irohin wipe awọn Egungun meji ba ara wọn ja nilu Ijẹbu-Ode, ekini pa ekeji. Dokita to yẹ oku na wo sọ wipe, on ri oju ọgbẹ kan ti o wọ inu oku na lọ tara ni ẹgbẹ osi bakanna ni on tun ri apa ọbẹ ni ejika osi on tun ri ọgbẹ kan ni ejika ọtun loju ti on, giri ati ipa lo wọ ọ ti o mu ki Egungun na tete ku.

Egungun to ṣe jamba na rojọ wipe, o ti to iwọn ọdun meji nisisiyi ti gbolohun asọ ti bẹrẹ larin emi pẹlu Nuga (Egungun ti o ku lo njẹ Nuga) Ija na si bẹrẹ lati ile Kasunmu Alagba (Olori Egungun) nitori ninu ile rẹ ni gbogbo Egungun ma npejọ si. Nuga lo kọkọ wa mi ni ija wipe mo ti di oku'gbẹ nitoripe emi ko le ṣe gẹgẹbi mo ti nṣe ri. Nigbati mo gbọrọ yi, inu bimi jọjọ mo si fi kumọ ọwọ mi lu u lati gbana wa, ni a ti di ọta ara wa.

Ninu Egungun ọdunni bi mo ti mbọ pẹlu awọn Egungun yoku, bẹni Nuga wa fa mi pada o gbe ẹsẹ le mi ni ẹhin ọrun, emi pẹlu rẹ si wọya ija o gbe mi la mọlẹ loju gbogbo enia ni mo ba yọ ọbẹ jade ninu apo, mo si ṣa ni ọbẹ lọna mẹta. Nigbati ẹjọ na de ihin ni adajọ ba yẹ ẹjọ na si igbamiran.

**THE NATIONAL BANK**
**Of Nigeria Limited**

Incorporated in Nigeria in 1938
Paid up Capital £1,130,000
Bankers to the Western Region Government of Nigeria
HEAD OFFICE
37, MARINA, LAGOS NIGERIA

22 Branches throughout Nigeria including
IBADAN, ABEOKUTA, IJEBU-ODE,
OSHOGBO, OWO, ONDO, ILESHA,
ILARO, BENIN-CITY, WARRI,
SAPELE ABA, KANO, ZARIA, JOS

LONDON OFFICE

1 THROGMORTON AVENUE. E.C. 2.
Manager: F. O. Tyrrell.

Telephone: London Wall 4303
Cables & Telegrams Natbaniger London.
Head Office Representatives in London
E. Akinwunmi Doherty.
CORRESPONDENTS
NEWYORK, PARIS HAMBURG.

## Nwon Fe J'oye Bashorun



**Ẹniti a nwo ninu aworan yi ni Oloye Sanni Kasumu Gbajabiamila, Keji, ni yio jẹ oye Bashọrun Olowogbowo ati ilu Eko pẹlu oke Ebute Metta ni ọjọ ọsẹ 8th March 1959.**

Awọn Bashọrun to ti njẹ niwọnyi : -

1. Baba Tiamiyu Savage lo kọkọ joye Bashọrun Eko fun Ogoji Ọdun, o si ku ni ọdun 1919
2. Lemomu sanni Onigbanjo jẹ lati 1919 titi di ọdun 1925.
3. Kasumu Gbajabiamila jẹ lati 1925 si ọdun 1930
4. Abudu Ramonu Aranmoleti-ẹsọ Williams je titi di ọjọ 21st osu Oct. 1931.
5. Musa Aleshinloyẹ Williams je lodun 1931 o ku ni odun 1947
6. Alhaji Muhamed Mustafa je lati odun 1948, titi to fi w'aja ni odun 1958.
7. Sanni Kasumu Gbajabiamila ni Bashorun keje to ti je nilu Eko lati odun 1919

iṣẹ atun aburada ṣe ni oloye yi kọ nṣe pelu baba rẹ, nwọn a si ma ṣe Aburada oba ati t'awon Ijoye. Lẹhinna iṣẹ atun kekeṣe (Bicycle Repairer) ati awon irin-iṣẹ

(Wo yoku loju ewe kejọ)

# Ojo Ibi, Ojo Ayo.



O ti siwa leti feren wipe Oloye Obafemi Awolowo yio se ojo ibi re laipe yi, awa Oniwe Irohin Eleti-Ofe f'eyi ki Asiwaju wa na, Olojo ibi pe Barika ! Barika!!, ki Olorun da emi re si fun opolopo odun ti o mbo ati awon ebi re.

Adajo so wipe on fi onte le ode na ki o lo so agbeje moni fun osu mejila, ti on ko gbodo ti ese te inun kotu mo. Adajo na gba ode na nimoran wipe, bi o ba je wipe emi ni iwo, nko tun ni gbe ibon mo depo ti mo se ode.

## Rotimi Williams Da Asikiwe Lohun

Oloye Rotimi Williams da Dr. Asikiwe lohun, o wipe, ofin ti lioba Iwo Orun ba ti se, ko si eniti o le yi pada. Ati gegebi Asikiwe ti seleri pe, nwon o gbe ero na de kotu, iyen jeki inu on dun.

Sugbon ohun ti iba mu daraju ni wipe, ki nwon jeki okan nnu awon egbe



Alakuko lo towo te ofin ijoba Iwo-Orun leti, nigbana yio mo pe kete ko nse awo.


## CARSON PAINTS AND VANISHES




SOLE AGENTS:-

IKORODU TRADING COMPANY
20 & 28, Balogun Street, Lagos.



EMA KA IWE IROHIN ELETI - OFE
L'OSOSE O KUN FUN IROHIN ALADUN


## Ode Kan Ri Oro Oloju Kan, O Yinbon Luu

IBADAN. Bi okunrin ode kan ti nse ode lo, beni o ri ohun kan ti o loju kan eru ba a beni gbami-gbami ko ye agba kini kan nle mi bowa koye ode, o ba gbe ibon re o yin lu u nigba aiya. Nigbati ibon na ti se ise ti a ran tan nigbana ni okunrin ode na to wa mo wipe ore on ni on yinbon pa.

Nwon gbe oku okunrin na lo si juri Dokita so wipe eje ti o tete tan lara re lo jeki o ku ohun ti o si fa ti eje fi tan lara re ni ibon ti nwon yin lu u Ode na so wipe ibon na sesi ni.





# Omo Ile Igbo-mina Edibo Fun Egbe Igbo-mina Parapo

Olotu,

Jọwọ gba mi laye diẹ lati fi ọrọ yi si awọn ọkawe rẹ to wa ni Igbo-mina leti fun idibo tombọ yi, ki Ọlọrun Ọba fi ẹmi wa di igba na kio bawa ni alafia ati ara lile.

Ako ọrọ mi si awọn enia wọn yi nipe, ki gbogbo yin mura kiẹ tete lọ fi orukọ silẹ fun idibo ti ao di wa ni apapọ ile "Nigeria" Federal Election" ninu ọdun ti a wa yi ki Oluwa fi ẹmi gbogbo wa di igba na.

Lẹhin bẹ, ti ẹ ba fi orukọ na sile tan, tio ba wa di igba idibo, kiẹ wa dibo na fun Ẹgbẹ Afẹnifẹre (Action Group) Igbomina Parapọ eni to ba wa ni Ilọrin, kio dibo fun Ẹgbẹ Talaka Parapọ asopọ mọ "Action Group" bakanna ni.

Ko tilẹ yẹ pe kia ma sọ n'kankan fun yin mọ nipa o'un ti a fi nke fun yin lati dibo fun Ẹgbẹ Afẹnifẹre (A.G.) gbogbo rẹ loti ye yin, o si ti han si yin pegede.

Mo si ti mọ daju daju pe ọmọ ale enia ni yio fi Ẹgbẹ Ọlọpẹ (A.G.) silẹ ti yio wa dibo fun Ẹgbẹ Olomi (N.P.C.) o si da mi loju pe gbogbo awọn ọmọ ibilẹ Igbomina yio dibo fun Ẹgbẹ Ọlọpẹ (A.G.) ṣugbọn eyi to ba jẹ ọmọ ale wa le dibo fun Olomi (N.P.C.).

Mo bẹyin ni ọkunrin, ni Obinrin, ni ọmọde, ni agbalagba ati awọn alejo na, kiẹ dibo fun Ẹgbẹ Ọlọpẹ (A.G.). Ni Ogo Oluwa, ọwọ wa yio si tẹ n'kan ti a nwa, ẹnyin papa ti mọ ohun ti a nwa, ko tilẹ yẹ pe kia ma sọ fun yin mọ.

(Wo yo ku loju ewe karun.)

# AWON ONISE IROHIN IJOBA

Awon ti a nwo yi ni awon enia dudu ti ijọba ran lọ silu oyinbo lati kọ iṣẹ bi a ti nṣe irohin fun Ijoba (Information) awon enia na ni a nwo wonyi ni igba ti nwọn lọ ṣe ayewo ọgba ile Afin ọba ilu Oyinbo. Ẹniti a nwo ti o de fila Tomi, ti o si wọ aṣọ dudu ni ẹgbẹ osi ni Ṣọja ti o nṣọ ẹnu-ọna Afin ile ọba.



# ORIN OMODE

Woru o woru oko,
woru o, woru odo
woru na'kọ f'ẹyẹ je
mo dele mo ro fun
Baba baba na
woru jọ'ọ, woru
da ? ogun gba lọ !

# ELETI - OFE

A-NJU-WỌN KO ṢE WI L'ẸJO

EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM

28, Kakawa Street, Lagos "ELETI - ỌFẸ LAGOS"

P. O Box 467 Phone 23370

VOL. XI. NO. 614. SATURDAY MAR. 7 - MAR. 13, 1959.


## Iro Npuro Fun'ro ...

Ṣigidi ko lẹnu, o ni on yio sọrọ, irọ l'o npurọ fun-'rọ ni ede ti a le sọ si gbogbo ọrọ agadamaṣa ti aṣiwaju ẹgbẹ Alakukọ, Dokita Nnamdi Azikiwe ti nsọ kakiri ilẹ Iwọ-Orun, nipa wipe pẹpẹsẹ bi nwọn ba dibo fun ẹgbẹ on, iyen ni ẹgbẹ Alakukọ, awọn yio sọ oke dilẹ awọn yio ṣe ohun ti ẹnikan ko ṣe ri nitoripe ohun ti ijọba ipinlẹ kan ba ti ṣe ko si ẹniti o le yi pada, ayafi ijọba ti o ṣe ofin na nikan ni o lagbara lati ṣe ayipa rẹ. Gbogbo ọrọ adidun ti aṣiwaju ẹgbẹ Alakukọ na nsọ fun awọn enia, irọ patapata ni.

Laifọtape, awa le sọ gbangba wipe kosi ẹgbẹ kan to le di opo ijọba ilẹ Nigeria wa mu lẹhin ẹgbẹ Afenifẹre (Action Group) ikan ni ẹgbẹ Alakukọ (N.C.N.C.) tabi ẹgbẹ Olomi (N.P.C.) ati awọn isọngbe wọn, agba ofo ni gbogbo wọn jẹ, ti o ma npariwo.

Nitorina, kosi ẹni meji ti a le fi ọkan tẹ, ti o si to gbẹkẹle ju Ọlọla Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ lọ, bi ẹnyin enia wa ko ba fẹ jo ilu agbaṣina-dan, ẹ jẹki a dibo fun ẹgbẹ Afẹnifẹre, ki a bomi pana awọn opurọ.

Ẹ dibo fun ẹgbẹ Ọlọpẹ (Action Group).


## Imoran Fun Enyin Abiyamo

Enyin Abiyamọ ẹ wa ra ỌMỌRẸLA, o dara pupọ fun awon ọmọde.

Ama jẹ ki ọmọde ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati oriṣiriṣi arun miran ti o ma mba ọmọ ja ni asiko ehin. Ọpọlọpọ abiyamọ lo ti lo egbogi yi fun ọmọ wọn ti won si sọ wipe o dara pupọ fun awọn ọmọde

ỌMỌRẸLA BABY MIXTURE

(Ṣile Meji Abọ 2/6d Fun Igo Kan)

O wa Lọdọ

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemists)

10. VICTORIA STREET, LAGOS.


## 1959 Pilgrimage

### VACCINATION CERTIFICATE REQUIREMENTS.

All persons intending to leave Nigeria on the Pligrimage are reminded that they should be in possession of valid International Certificates of Vaccination against:

(1) YELLOW FEVER

(ii) SMALLPOX

(iii) CHOLERA

and are advised in their own interest to take inoculation against typhoid.

YELLOW FEVER VACCINAION SHOULD BE TAKEN FIRST

The addional requirements of the Sudan Government of all pilgrims leaving the Sudan are that:-

(i) the International Certificate of Vaccination against smallpox should be less than one year old.

(11) The International Certificate of Vaccination against cholera should indicate that two injections have been given at an interval of seven days, the validity starting from the second injection.

(111) All persons are required to hold a certificate of Inoculation against typhoid. The first dose to be 1/2 c.c. and after 7 days a second dose of 1 c.c. the validity of this certificate will start 6 days after The second dose. The particulars should be filled in the booklet of International Certificates under " Certificare of Other Vaccinations, " In the case of re-inoculation, which should be done one year after the primary inoculation a single dose of 1/2 c.c. is required, and such a certificate is valid on the same day.

## Owe Yoruba

Ilara alaju lo nmu wọn gba'jẹ, to nmu wọn sẹṣo
Nini sunwọn l'ejo, ara nta ọka, ọka roju koro-koro,
bẹ Nini ko jẹ bọ aṣọ rẹ silẹ ki o gbe fun ọka.
Ekolo nmi igbago inu mbi adiẹ suṣu,
adaba ko nani a nkun igbẹ, bina ti njo ni ẹiyẹ
oko nfo lọ.




# NISISIYI !

FUN IGBA AKOKO NILE NIGERIA...

AWỌN ONIṢOWO

**THE NIGERIAN GAS CORPORATION LTD**

YIO MA ṢE

ETO OHUN IDANA GAS SINU ILE LATI MAFI DANA

Ale fi Gas pẹlu Meter rẹ sinu ilé ti a ngbe. Koni agbekiri. Ko si ni ṣalai muna wa nigba kan. Ko lewu, o rọrun, lilo rẹ din inawo ku.

ẸNYIN KỌLEKỌLE, ONILE ATI ẸNIKẸNI TI O BA FẸ LILO RẸ KI O KỌWE FUN ALAYE KIKUN LỌDỌ :-

**NIGERIAN GAS CORPORATION LTD.**

2, IJAPEJU AVENUE, P.M. BAG 1040 APAPA TELPHONE 55295,

Iye owo rẹ ati gbogbo alaye nipa rẹ ni ao ṣe fun yin lọfẹ.



**Plushes, Velvet, Velveteen, Damask & Building Materials.**

PLEASE CONSULT

**Okunowo Brothers**

63, Massey Street. (Faji Market)

LAGOS, NIGERIA.

The House where Courtesy & Satisfaction are Guaranteed


## Won Bi Abami Omo Nilu Oyinbo

ILU OYINBO. Irohin kan wa pe, obinrin kan ti o nṣe iyawo Olotu Bank (Bank Manager) ti o ngbe ilu Hendon lo bi ọmọ mẹta ni ikunlẹ kanṣoṣo. A gbọ wipe awọn meji ninu awọn ọmo na sopọ ni awujẹ.

Awon ojọgbọn ninu iṣẹ iṣegun (Pathologist) forikori nipa gẹgẹbi nwọn ti ṣe le ya wọn si ọtọtọ ti awọn mejeji ko fi ni ku. Gbogbo ẹya ara yoku lo mbẹ ni ọtoto, won ko ri ona ti nwon legb egba.

Ijoba Gẹsi paṣẹ wipe ki a jẹki awọn ọmọ mejeji na ma bẹ ni alafia ki nwọn si ma dagba papọ. Orukọ ekinni a ma jẹ Timothy, ti ẹnikẹji rẹ a ma jẹ Jeremy, orukọ iya wọn njẹ Kathleen. Ibikibi ti iya awọn ọmọ na ba gbe wọn de ninu kẹkẹ, awọn enia yio pejọ lẹ wọn lori lati wo iṣẹ iyanu Ọlọrun, olukuluku enia ni yio ma fi owo ta iya ọmọ na lọrẹ.

## ỌMỌ ILẸ IGBOMINA ẸDIBO FUN ẸGBẸ IGBOMINA PAKAPỌ

(O bere loju ewe keta)

Gbogbo yin ni ẹ ri ni gbati wọn wa ṣe iwadi ẹya ilu kekeke, koṣe bojuboju si ẹnikan bẹsini ẹ ri ohun ti awọn aṣoju wa babọ lati ilu Oyinbo, koṣe bojobuju si ẹnikọkan. Ohun ti awa le fi gba fi gbara wa silẹ lode yi, kia wa mura gidigidi ki Oluwa gbe wa ga ninu ibo na, kia si kuro labẹ awọn Gambari.

Ẹnyin Ọmọ ilẹ Igbomina ti o nṣe ẹgbẹ Olomi (N P.C) ẹ ja wọ kuro ninu apọn ti koyọ' ẹda omi ila kanọ, ẹ kuro ni ọna iṣina ki ẹ bọ si ọna to jẹ otitọ, ọna to jẹ otitọ na ni ẹgbẹ Afẹnifẹre (A.G.) kiẹ jọwọ kiẹ dibo fun Ẹgbẹ Afẹnifẹre, maṣe dibo fun Ẹgbẹ Olomi (N P.C).

Ẹ ma jẹki awọn ti ko mọ nkankan ṣi yin lọna, tiẹ ba le gba tiwọn, eso buburu ni ẹgbin silẹ fun ọmọ yin yẹn o. Ki Ọlọrun majẹ kia ṣe aburu silẹ fun awọn ọmọ wa o.

Kiẹ jọwọ kiẹ tete lọ fi orukọ silẹ, ki ẹ si dibo fun Ẹgbẹ Afẹnifẹre ni ọjọ na o.

Emi ni
Y. Ade Buramọh
Ọmọ Ọtun-Oro

## WON RI OBINRIN TO SONU NI DAHOMI

KALABA Ni won ọdun die sẹhin ni a gbọ irohin wipe Obinrin kan ti nwon npe ni Rosaline pelu ọkọ re jijo lo si oko nwon si wa a ti, oko Obinrin na ti o nje Uche ara Bẹnde sọ wipe on ko tile le so ohun kan ni iru ọna ara ti iyawo on na gba sonu lasiko ti awon lo kọ ọpẹ ninu oko won.

Ni ojo kan ni awon aladugbo re ti o lo se owo nile Dahomi ri Rosaline, agbara kaka lo fi gbo ohun ti nwon mba sọ, ede awon ara ile Dahomi lo so lenu Nwon pe e ni oruko re, agbara kaka ni o fi mo pe on ti njẹ Rosaline ri, o tilẹ fere ma gbo ede awon Bende mo, ni nwon ba mu lo sile.

Inu okọ rẹ dun lati ri i, awon omo re si yọ. Nigbati nwọn bere lọwọ re pe kilo ti rin ki o to de ile Dahomi o dahun pe on kele so yala ibi kan ni agbe bi on. Sugbon nigbati on ri awon enia ti o npe on ni Rosaline ti nwon si mba on so ede ni ori on bere si yi wa sile die-die.

## Angeli Kan Fe Sokale Si Okun Alasia

Olootu,

Ni ojo kini osu March nigbati emi wa ni ijo, beni agbalagba Padi kan yo simi itungbon re kan ni nigbaiyi, o pe mi pe Tola kini iwo nibiti ti ko pe mo wa sihin lati wa ojuran Olorun ni o wi fun mi pe mo i ri i na ki ...

O se fun mi pe bi o ba je pe ... mo ... Jesu gbo ki ... gbogbo omo egbe Serafu ... ki nu ... fun won pe ... o ba di ojo Sunday 22nd March 1959 igba ... ni emi ti ... re nje EL-YA-OM yio sokale si okun Alasia. Apere ati Ibeju.

Nitori na gbogbo awon emi ore ba ... ti o pade on nibe lojo na Padi ... maria gegebi awon ... Mo bere lowo re pe ... yio je simi wiwa tabi dide re. O dahun pe nigbati gbogbo re ba pa lolo, ti a ngbo ohun ti awon ti mbe ni okere nso nigbana on mbe lodo won.

Mo so fun pe ki o fun mi ni eri. O ni ki ngbe mi o si da ... simi lowo gbogbo owo mi si dabi ti omo titun. Mo gboro pe ... mbe lehin mi bi mo si boju wo ehin, nko ri ohun kan nigbati mo si gbe oju pada, okunrin na ti lo ... si ba mi.

Emi ni
Oko-moji

## Iyafin Kutti Tun Lugbadi Ijoba Egba

ABEOKUTA Iyafin Funmilayo Kuti ti o nse Iyaegbe awon obinrin Egba ati okan pataki ninu egbe Alakuko (N. C. N. C.) ni awon olopa mba se ejo ninu kotu Ake (Grade "A" court) fun esun wipe, o di awon onise ijoba lowo lenu ise won.

Akoko ninu esun ti awon fi sun obinrin na ni wipe, Funmilayo ko jeki awon eni meji kan ti awon fe sanwo ori san a, ati ekeji ni pe o di awon olopa oba lowo lenu ise won.

Adajo kotu bere pansi wa lowo Iyafin na, sugbon o ye ojo igb'ejo oro na si ojo 10th osu March 1959. Ki Iyafin na to lo sinu ogerun Poun, pelu oniduro kan.

## Ijoba fi Ijoye Ilu Ejigbo joye Adajo Kotu Ibile

EJIGBO. Ijoye kan ti o nje Yesufu Ojelola Asolo ti o si je wiwo ni oun Elejigbo ni Ijoba Iwo Orun yan si ipo Adajo agba ninu Kotu ibile Ejigbo ti awon si se iwuye-wuaye fun wipe, ki o wa bura pe on ko ni fi ejo segbe.

Ijoye Asolo yi ti to eni adota odun nigbati o gun ate idajo adajo agba yi.

Nigbati o mbura, o se ileri wipe on yio se ise on gegebi on ba ti to, on ko ni fi ejo segbe, on ko ni gba ejo alare fun elebi, beni on yio korira owo ehin ati owo abetele.

O ti wa mma awon adajo kekeke ti o ti nda ejo ri fun awon odun melogun, awon Ijoye ti a tun yan lati se iranlowo adajo agba kotu na ni Oloye Yesufu Ogunwole, ati C. L. Bello.

Awon enia ti o wa sibi ifijoye na to edegbeta enia Oloye ti o wa jawe oye le awon enia na lori ni Ogbeni P. C. Segbesan, Onimoran Ijoba Jati ilu Osogbo.

## Onigbese Data S'olowo loju

Pota. A gbo irohin wipe okunrin kan ti o njo Chigbuo lo sile onigbese re lati gba owo na lowo re Money kan, owo na si je poun kan.

Onigbese bere pe, ki lo fe ogbeni Chigbuo si dahun pe, kilode bi ti owo, owo mi ni mo wa gba! hum kinla! ni owuro kutu-kutu ojo Monday ... bi okunrin onigbese na tobe, ti o fi ... lowo bo ata ti o fe fi se obe, o si jan a mo olowo loju.

Ile ni oro na bacegun ti awon olopa. Nigbati oro na dewaju adajo okunrin onibese na gba wipe nitoto ni on yen ata mo loju sugbon esu lo tan on si ise buruku ti on se na, adajo ... pe ki o lo gbewa osu mefa.

Kere o !

Ati ni orisirisi o g u n German to sese de, fun oniruru aisan tokunrin tobinrin. Tete wa ra tire ki o to tan.

J. A. AJAO BROTHERS

MEDICINE STORES
7, Egerton Road Lagos

# Dr Asikiwe Fe Tako Ofin Agbegbe Iwo-Orun



Olori egbe Alakuko Dr Azikiwe, ni Ijoba Iwo-Orun se ikilo fun wipe, o lu ofin Ijoba Iwo-Orun lasiko ti o lo si Ilesha. Ohun ti asoju Alatako ati Olufisun ti Ijoba Iwo-Orun se ni pe o kowe si Dr. Asikiwe nilu Warri pe awon fi eyi se ikilo fun Asikiwe nitoripe o ti soro ti o lodi si ofin ijoba Iwo-Orun, eyiti o je wipe bi o ba se abori kura kan lo so iru oro be, olopa ni iba mu.

Oro ti o so ti o lodi si ofin na sele ni Ilesha. Oro ofin na si lo bayi wipe, Nigbati ijoba Iwo-Orun ba ti gba enikan gegebi Ijoye enikeni ti o ba, tun lo fa ijogbon nipa oye na lu ofin Ijoba yio si wo ewon odun meji.

Ofin yi ni Asikiwe jiyan le lori pe, ko to sunn rara. ko si fen ni laye lati soro enu eni jade lasi ijaiya.

ELETI - OFE DARABA




# Orin Ijo Agbe

Bi ẹ ba ngbọ pekelebeke, ẹ ma ya lotun ẹ ma ya losi, ile oniyawo ni k'ẹ malọ, Bi ẹ ba ngbọ hẹn, hẹn, hẹn, awa ni-awa ni Bi ẹ ba ngbọ hun, hun, hun awa ni-awa ni Bi ẹ ba ngbọ fere lode o, awa l'ode o.

## ELECTRICITY CORPORATION OF NIGERIA

### INVITATION TO TENDER

METER ROADS

The Electricity Corporation of Nigeria invites tenders for the supply of 1,000 herd wood meter boards, 18 ins. x 9 ins., to be delivered to the Chief Store-keeper, E. C. N. Central Stores, Ijora.

A specimen meter board can be inspected at, and a dimensioned sketch obtainable from, the Central Stores, Ijora.

Delivery of the meter boards will be required over a period of four months in accordance with instructions to be given to the successful contractor by the Chief Store-keeper.

Tenders should be forwarded in envelopes marked "Confidential - Tender for Meter Boards" to reach the Secretary, Electricity Corporation of Nigeria, Electricity Headquarter, 13, Broad Street, Private Mail Bag 2030, Lagos, not later then 12 noon on Saturday 14th March, 1959.

The Electricity Corporation of Nigeria does not undertake to accept the lowest or any tender.

## IROHIN AWON OLOṢA TO PANIA NI IDI ARABA

SURU-LERE. Ọkunrin lebira kan lo nrojọ niwaju adajọ ninu kotu arufin Eko. Awọn mejeji yi Kalu Udensi, ati Awudu Yola ni awọn ọlọpa fi sun ẹsun wipe, nwon lo jale, nwon pa onile.

Ọkunrin lebira yi, ti oruko rẹ njẹ Asani Kalabu. Kalabu ni gbogbo oro na soju rẹ on lo wa tu perepere sile bayi pe;-

Bi mo ti jade kuro nibiti mo gbe lọ mu emu, niwọn agogo kan owurọ, mo ri Awudu Yola ti o pe mi pe ki ntele awọn lehin kalọ. Yola nlọ niwaju emi ati Udensi mbu lehin. Nigbati a de iyana ti o lọ si Suru-lere, Udensi bo siwaju emi ati Yola mbo lehin.

Nigbati a de ibi ibile kan ni egbẹ Ṣọṣi, Yola ni ki a duro emi ati Udensi duro ni ode gbangba. Yola lo si egbe ile kan, o si ferese re o si wole. O gbe apere kan fun Udensi lati inu ile na. Yola tun nfe gbe apoti kan jade pelu ni mo gbọ ti enikan kigbe ole! ole! ole! ninu ile na, nigbana ni emi ati Udensi ba salọ.

Ni ojo keji ti mo ri Yola, mo bere lowo rẹ pe bawo lo ti rin ti owọ ko fi tẹ ọ? O dahun pe ose ni on gba'ra on silẹ. Bi nwọn ti di mo on ni on si ya won ni obẹ. Nihin ni adajo sun ọjọ igbẹjo na siwaju di ojo keji nitori ile su.

## Itan Elegbeje Ado

### AWON EBORA BERE ORO

Ę n koko soro ni Ębora inu ariba .o ki gbogbo awon elegbe re, o si tun ki o-de Elegbeje-ado o ni pipe ti a pe loniyi, ki ise fun ti ija bikose kia ran Ogbeni toje ajoji ninu wa nibiu lowo, ni oru ano, ni mo ri to joko ori mi ti o nsi nyo mi lenu ni mo wa jade si, mo mura lati baja ni, sugbon oro to jade lenu re dara pupo o si wa sope on fe iranlowo lati odo awon Ębora to je oninure e igbo yi mo si wa fun ni esi pe emi ti mo duro yi mi o ja mo akankan ninu awon ębora inu igbo yi, ohun to se ti mo fi pe enyin alagba mi ni yio.

Olori won wa dahun pe, ko ye ki a ma gba oro na gęgę bi igba oti rara, kini o wa wa si inu igbo yi? ki a-to mo ohun ti ao se fun e.

Elegbeje-ado dide o ni mo ki yin lomode lagba ati saraki-saraki inu inu igbo yi, ohun ti mo ba wa si-nu igbo yi ni pe. mo fe gbe ogun ti ebora osudun, ki Olorun oba si fi le ni lowo ki nfi ęgun re.

Olori Ębora:- Anu se mi fun iwo ogbeni yi, opolopo elegbe re lo ti wa gbogun ti, ti o si pa gbogbo won, ti won ko de ile mo rara, sugbon ni agbara Olorun Oba, gege bi o ti ni agbara to, iwo yio ęgun re, to ri pe, o nyo awa papa na lenu pupo, ko je ki a ni isimi rara, ninu igbo yi pipa lo npa awon omo wa ję gęgę bi adię, ona ti o le gba ni yi, ti o ba di owuro ola, ki o fi owo osi re na igi to wa ni okankan rę yen, iwo yio si ja si ehinkule rę.

Koiti pari.

## Iwe Ayipada Oruko

Olotu. Mo si pe pelu ola ati owo lati se ayipada oruko mi, ninu ikede iwe ibise yin. Fun isileti yin, mo nilati so fun yin wipe mo bere ise ni Department of Commerce and Industries ni October 1957, lati igbana ni mo ti nje Julius Adegbole. Ni September, odun ti o koja 1958 yi ni o han si mi wipe oruko oye ni Adegbole ise, enia kankan ko si gbodo je oruko yi afi eniti awon Ekiti District Council ba yan. Ni kukuru, mo fe ki e ba mi paro oruko mi si Julius Bodunde ti 142 Tokunboh Street, Lagos. Bi e ba ba mi se ise mi yi, emi yio dupe gigigidi lowo Alakoso ile ise yi.

Emi ni tiyin nitoto,
JULIUS BODUNDE.


**E MA KA IWE IROHIN ELETI - OFE**

'L'OSOSE O KUN FUN IROHIN ALADUN

ARA-O-LIN - IPARA ATATA




ARA-O-LIN je ipara ti o gbamuse. O tayo gbogbo irufe egbogi bee ti o ba l'oja. O dara fun lakuregbe, egbedidun, aranlatanlatan, eśin-didun, iburadi-sise, arinka-inu-egun ifi apa tabi ese ro, efori, inlu, otutu-aiya, otutu-agbari, ikun-didimu, orun-didun ati origirisi aisan kungekunge bawonni. Nitori werewere ti o nta, awon Yoruba npe e ni "ATA", Ibo npe e ni "OSE" Hausa si npe e ni "BOROKONU". Dan igo kan wo ni 2s. 6d. (oto fowo-oko) lati mo bi o ti ri Kosemani ni.

The Egba Trading Aradan Stores,
18 Denton Bridge St., P. O. Box 2, Ebute-Metta.


## NWON FE J'OYE BASHORUN

(O bere loju ewe kini)

Basikulu fun tita l'o tun nse. A si tun ma ranse Basiku ti nwon npe ni New Hudson fun tita pelu.

On si ni Baba egbe awon Ęlęro-ogi, ero ti o nlo agbado lati Eko ti o fi de ilu Ibadan.

Oloye Sanni Kasunmu Gbajabiamila yi ti dagba to eni odun merinle-ladorin ki o to gori Oye Bashorun Eko.

Ki emi ola pe o.


# "DYNAMIREN"

The World Renowned German Nerve Tonics




"Dynamiren" Sets Your Vital Forces In Motion – A Product In Front Of All.

PRICE 12/6 POSTAGE 1/6

Stockists :

NIGERIAN MEDICINE STORES,
Tinubu Bus Stop, Lagos, Nigeria.

COMMERCIAL MEDICINE STORES
10, Victoria Street, Lagos, Nigeria.

ALBAN PHARMACY LTD
2, Victoria Street, Lagos, Nigeria.

**Waterloo Medicine Stores**
8, Palm Church Street, P. O. Box 333
Lagos, Nigeria. Phone 22878.


Printed & Published by The Union Printing and Publishing Cmpany 28, Koso Street Lagos P. O. Box 467 Phone 23370